# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI ỌGBOGBO LAWA

No. 565 THURSDAY, MARCH 26, 1964 (2D)


## Awọn Igara Ọlọṣa Kan Ko Ẹru Sinu Ṣọọṣi

POTA:— Idaamu nla ba gbogbo awọn enia ti ile wọn wa ni adugbo Ṣọọsi kan ni Diobu, ilu kan ti ko jinna si Port Harcourt pupọ nigbati awọn Ọlọpa ri awọn ẹru Olowo iyebiye kan ti awọn Ọlọṣa jiko ninu Ṣọọṣi kan ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi.

Irohin awọn ọlọpa fi ye wa wipe nigbati awọn gburo awọn ọlọṣa na ti nwọn ru ẹru kan ti awọn si ni ifura si, ni awọn ba bẹrẹsi wa gbogbo awọn adugbo na kakiri.

Irohin na tun ṣe alaye wipe, ko si ọlọpa ti o ri awọn ole na nigbati nwọn nko ẹru na lọ, ṣugbọn nigbati irohin de si etigbọ wọn wipe nwọn ji awọn ẹru kan ko, ni Erekusu Fernando-Po, ni awọn ba bẹrẹsi wa gbogbo adugbo kakiri.

Ọkan ninu oga awọn ọlọpa na fi ye wa wipe, ẹgbaa mẹrindinlọgbọn ponun (£52,000) ni iye owo awọn ẹru ti awọn ọlọṣa na ji gbe. Nigbati awọn si bẹrẹsi wa awọn ọlọṣa na ati ẹru ti awọn ji ko, ni awọn ba wọ inu Ṣọọsi kan ti awọn si ba gbogbo awọn ẹru na ninu Ṣọọsi.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn ọlọpa na b a owa ile Oniwasu Ṣọọsi na kakiri, ko pẹ lẹhin na, ni ẹnikan ba juwe ile rẹ fun wọn, awọn ọlọpa ti mu Oniwasu na, nwọn si ti ko awọn ẹru na lọ si Teṣan.

Nigbati oniwe irohin wa ni Pọta bere oruko Oniwasu na, ọga awọn ọlọpa kọ lati sọ orukọ Oniwasu na. Bi nwọn ba ti pari rẹ si, ẹ o maa gbọ o.

## Azikiwe Kigbe Pe:

# ẸNYIN OLOYE AMOFIN HA DAKẸ Ẹ NWORAN NI?

### Ẹnyin Alakoso Ijọba Tabi Ẹ Ko Mọ Pe Itakun To So Igba Lo So Agbe On Na Lo Tun So Elegede

### Pẹlẹpẹlẹ Di Ọwọ Ẹnyin Ara Ilu!

EKO:- Ọlọla Dọkita Nnamdi Azikiwe, Olori Apapọ Ijọba Naijiria ti tun kesi gbogbo awọn enia orilẹ-ede yi lati maa ṣe pẹlẹpẹlẹ lori bi gbogbo nkan ti ṣe nlọ ṣegeṣege ati lai ko fararọ ni orilẹ-ede yi lati bi ọjọ mẹta ṣehin lati igbati abayọri eto ikania ti jade

Ọlọla Azikiwe sọ pe, "Ẹnyin Amofin, ẹ ha nworan ni ?, Ẹnyin Alakoso Ijọba, tabi ẹ ko mọ pe itakun to so igba, lo so agbe on na lo si tun so elegede ?"

Ọrọ yi ni Ọlọla Azikiwe mba gbogbo awọn Alakoso Ijọba ati awọn enia orilẹ-ede Naijiria Alailọba sọ ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi.

Ọlọla na nsọ ọrọ yi lori rukerudo ati isọko ọrọ si ara ẹni larin awọn enia Ipinlẹ Ariwa ati awọn enia Ipinlẹ Ila Orun Naijiria.

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe, eyi ni igba kẹta ti ọlọla Azikiwe yio kilọ fun awọn enia orilẹ ede yi lati ma huwa pẹlẹpẹlẹ, ki gbogbo enia o si ma a huwa si ara wọn gẹgẹbi ọmọ iya kanna.

Ọlọla Azikiwe ṣe alaye fun gbogbo enia pe ki on to bọ si ori oye Olori Apapọ Ijọba Naijiria on ti ṣe ibura pe on ki yio ya oju on silẹ ki talubọ o ko si i

Bẹni gẹgẹbi ofin iṣelu orilẹ ede yi mo ti ṣe ibura, mo ti ṣe ileri pe ngo ma a ri si gbogbo awọn ti o nhuwa aibọwọ fun ofin Orilẹ ede yi awọn ti yio ma tẹ ofin leti, nipa aimọkan wọn tabi nipa orikunkun.

Ninu gbogbo ohun ti o ti nṣẹle ati eyiti o si tun nṣẹlẹ lọwọ bayi, awọn miran ti nfoiya nipa aṣẹ ati agbara ti nwọn ni ni orilẹ-ede yi.

Lati igbati gbogbo nkan wọnyi ti nṣẹlẹ, ni Orilẹ-ede yi, on lo asiko yi lati sọ ipilẹṣẹ bi ẹtọ Olukuluku eyi ti akọsilẹ rẹ wa ninu Iwe Ofin, ati lati kiyesi gbogbo ẹnyin Alakoso Ijọba ati awọn Olugbe Orilẹ-ede yi, pe ki Olukuluku enia o maṣe tẹ ofin leti

"Gẹgẹbi ofin iṣelu orilẹ-ede Naijiria, ẹnikẹni lo ni anfani fun ida aabo bo Ijọba lai ko si ninu ewu.

Ona mẹwa ni ọlọla Azikiwe gba ṣe alaye ẹtọ ti awọn enia Naijiria ni ni orilẹ-ede yi, ki Ijọba kanan npa tabi ọranyan o ma ba ṣe wọ orilẹ-ede yi.

Ọlọla Azikiwe ni, ẹnikẹni ko gbọdọ hu iwa ẹhanna si ọmọ ẹnikeji rẹ

Ona keji, ẹnikẹni ko gbọdọ fi ipa mu ẹnikan ṣiṣẹ ti ko ba fẹ ṣe, bi ẹnikan ba si fi ipa mu enia ṣiṣẹ ti ko fẹ ṣe, oluwarẹ ti a fi ipa mu le pe onitọhun lẹjọ labẹ ofin ni Ile-ẹjọ

Ona kẹta, ẹnikẹni gbọdọ lo ohun ti o ba ni pẹlu ifayabalẹ ati laifoya

Ona kẹrin ẹnikẹni lo ni anfani lati le gbe pọ pẹlu ebi ati awọn enia rẹ pẹlu alafia.

Ona kẹrin, ẹnikẹni lo ni anfani lati ronu ki o si sọ ero ọkan rẹ jade.

Ẹnikẹni lo ni anfani lati le sin ẹsin ti o ba wu oluware.

Ẹnikẹni lo ni anfani lati le sọ ero ọkan rẹ.

Ẹnikẹni lo ni anfani lati le ṣe ipade eyiti ko leba anfani elomiranjẹ.

Wo Oju Ewe Kẹfa



ỌLỌLA DOKITA NNAMDI AZIKIWE
Olori Apapọ Ijọba Naijiria


Wa Wo Ere

Ọlaọrẹ Afọtẹjoye

NI

METHODIST BOYS' HIGH SHCOOL, EKO

Ni 30/3/64, Ni agogo Meje Abọ

# NIBO NI AWA ỌMỌ YORUBA NLỌ?

**Lati Ọwọ R.T. Alaka**

Awa ọmọ Yoruba ti di bọlu ti nwọn ngba kiri bi o se wu wọn larin orilẹ-ede loni, lati ẹhin wa titi di ọdun 1962 ni gbogbo aiye nbu ọla fun wa gẹgẹbi iran ti o gbọn ti o si mọ ohun ti o yẹ



Oloye S. L. AKINTỌLA

Şugbọn laipe jojo awọn kan ti oti ta ọgbọn ori wọn ti nwọn si ti fi ọkanjuwa ara wọn goe ra wọn ta ti nwọn si nwa igbega ti wọn f'ọna eru da orile ede wa ru

Iru iwa bibura yi lo nfa irukerudo larin wa iowọ ba yi lati le sọ bi opin re yio ri

Gbogbo enia lo ti han si loju gbangba ni asiko ti Dọkita Maja ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ beresi lọ kakiri ọ d ọ awọn oba ile wa lati le yi wọn lọkan pada sinu ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin

Orişirişi ọgbọn ati ete ni nwọn fi yi awọn ọba ati ijoye wa lọkan pada lati le sọ irọ wọn di otitọ

Nwọn nsọ kakiri pe, o yẹ ki awọn lọ ẹgbẹ ọmọ Oduduwa lati le da ẹgbẹ miran silẹ ti yio ma gbẹnu sọ fun gbogbo awọn ọmọ Yoruba

Pẹlu gbogbo wahala wọn a ri pe Dokita Maja şe gbogbo ọna lati le yọ akọwe ẹgbẹ ọmọ Oduduwa eyiti ko şe şe fun un

Nwọn gbiyanju lati le yi ipade ti nwọn se ni Mushin si Ibadan



DOKITA AKINỌLA MAJA

tu na, ti yio si fi han gbogbo aiye pe, ki işe ilọsiwaju Ilẹ Yoruba ni ẹgbẹ Ọ m ọ Ọlọfin nwa.

Lati igbati Dọkita Maja ti bẹrẹ iwa yi ni o ti bẹrẹ si sare lati Eko lọ si Ibadan. B ẹ n i o si gbiyanju pẹlu lati le gba orukọ rere larin awọn ẹlẹgbẹ rẹ.

Dajudaju awa Yoruba ti o ni lakaye ninu ti mọ pe ile ti a ba fi itọ mọ, Iri ni yio wo o.

Awa ti mọ pe awọn Ọba kan wa ti nwọn nbẹru pe ki nwọn ma le rọ awọn ni



Oloye FANI—KAYODE

Ohan gan pe ninu awọn ọmọ igbimọ alabẹşekele ti ẹgbẹ Oduduwa ti şe ogoji mẹfa pere ni o tẹle Dọkita Maja lọ si Ibadan, ati pe mẹta ninu awọn ọmọ ẹgbẹ yi ni oti fi lẹ bora bi aşọ bayi.

Ibẹru lo fa ti ọpọlọpọ awọn Ọba ati Ijoye ti o pesẹ si Ipade Ibadan yi fi wasi bẹ.

Ipade ti Dọkita Maja şe yi ko fi han pe gbogbo ọmọ Yoruba ni o ni ife si ohun ti wọn şe.

Nitori pe awọn Oba alade meje wonyi lo gbọdọ pese lati sọrọ ọmọ Oduduwa,

Olowu ti Owu, Alaketu ti Aketu Ọ b a ilu Ibinni, Akenzua, Aranum ile Ila, Onisabẹ ti Isabẹ, Olupopo ati Alafin Ọyọ bẹni Awujale ti Ijebu Ode.

A r i dajudaju pe ninu ipade ti awọn ọmọ Ọlọfin şe ni Ibadan ki işe gbogbo awọn Ọba ni o pesẹ sibẹ. Pataki awọn ọba ilẹ Ijẹbu tilẹ Ekiti, ti ilu Eko ati awọn oba Oshun nibi ti ati bi oloye Akintọla tişe opo mulero ẹgbẹ Ọlọfin.

Şugbọn ni bi Ipade ti a şe ni Mushin ti o fi han pe ero nti wọ bi omi

Ati ri pe Dọkita Maja ti fi ọna ti ko dara fọ ẹgbẹ ọmọ Oduduwa si meji lati le ri wipe ile Yoruba kẹhin si ara wọn.

Aş ri iwa ibuburu yi fẹrẹ



Oloye OLU. AKIFOSILẸ



Oloye M. A. MAJẸKODUNMI

oye tabi ki enikan ma şe ba aye oye wọn je, lo mu wọn lọ şe ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin omiran wa onje lo, b ẹ ş i ni awọn miran wa owo a t i ọla lo.

Mo fẹ ki e mọ pe laipẹ ọjọ aşiri wọn yio tu jade.

Gbogbo aiye yio si ri idi otitọ

Ki Ọlọrun fun gbogbo wa ni ẹmi gigun.

# IWE SI OLOTU

## Imọran fun Hadji Imam Agba

Olotu,

Iwe Irohin Imọlẹ rẹ a maa kun fun irohin aladun ati irohin akakọ-ẹkọ ti o dara ju wura ati fadaka lọ. Nigbati mo ri ka nipa Olọtẹ baba rigimọ kan ti o jẹ ki nwọn da Lẹmọmu kan duro lai gbọ tẹnu rẹ nipa ẹsẹ ti nwọn ka si i lọrun, o ya mi lẹnu oju si gba mi ti.

Ẹsin Islam kọ Otẹ, o korira irufẹ iwa ibajẹ bẹ e. Pelu iteriba ni mo fi da-nimọran fun Hadji Imam Agba Ibrahim lati ṣe ofin ti o ba Ẹsin Islam mu ti yio si ko onirigimọ nijanu ni Mọsalasi Ẹyin Igbimọ Mọsalasi Jimọ, ẹ ran Lẹmọmu Agba lọwọ o

Emi ni
L. OJOGUN
Eko

## Ẹnyin Musulumi, f'eyis'ero

Mba ṣopẹ bi Olotu ba le gba mi laye lati kesi gbogbo awọn Musulumi jakejado gbogbo Ilẹ Naijiria lori ọrọ ṣegẹṣẹgẹ 'i eran ircn kiki mbọ ọ si ni ọdọọdun

Yio dara pupọ ti ẹba le fi odun Aawẹ ati Odun Ileya si ọjọ kana Otọtọ ni Ojọ na mbọọsi O yẹ ki gbogbo Ilẹ Naijiria maa kirun Aawẹ ni ni ọjọ kana ati Ọdun Ileya pẹlu Gẹgẹbi Odun Keresimesi ti ki taṣe ni ọjọ kanna.

Emi ni
TITILAYỌ ỌMỌNIYI
Okerimi-Oro

## Iwe Ijala Are Ọdẹ Dun Ka

Olotu, ayọ nla ni o jẹ fun mi lati kọ iwe mi yi jade fun tite nnu Iwe Irohin nyin aladun yi.

Mo fẹ lati fihan bi o ṣe dun mọ mi to nigbati mo nka iru ọna ti Ọgbẹni A. O. Adeniyi ti ṣe kọ nipa Iwe Ijala Are Ọdẹ ti Ọgbẹni Ọladipọ Yemitan ṣe.

Ko si ohun ti o dun to yi, mo fẹ ki Ọgbẹni Adeniyi gbiyanju lati le si awọn ti nka Iwe Irohin le ti nipa iwe Irohin leti nipa Iwe Ijala na die si.

Mo ni ireti pe ẹo ba wa ṣiṣẹ na siwaju si Olotu.

Emi ni,
SALAMI BAKARE
Ijẹbu-Ode.

# IWI ASIKỌ

Lati ọwọ: AFỌLABI ỌLABIMTAN

Mo tun de mo pegede o
Mo bọ mo fi gbọrọ jẹka
Emi opomulero b a b a
Ojẹtunde
Abanirẹ ma ni ni lara
Ẹkun ọkọ Ejide
Ori ọkẹrẹ koro lawo
Ba wi fun ọmọ eni
Ṣe o yẹ ko gbọ
Ba wi fun yekan katakata
O yẹ ko fohun sa-rimi
Mo sọ faiyekotọ perọ lo
ngaiye isiyi
O ni ki ngbẹnu sọhun o
jare
Bọga aiyekotọ ko ba si
ninu ile
Gbogbo ohun ba lọ lẹhin
ọga sisọ ni
Aiyekotọ daiye ko mọrọ pa
Baiyekotọ nbẹ ninu ile
Tọmọde taṣba aya ma ṣọra
N'tori ẹni abami, bọga wọle
A gbọ lẹnu aiyekotọ ẹiye
oluware
Benia petepero lọnu aiyeko-
tọ bu Esebiyi bi awo san
ju oluware
Ọga aiyekotọ fadaka sago
oforofo sinu iran
O ni alaisọtọ ni ẹiye adaba
O ni onike ekebe ni orofo
Ki nwọn ma gbe inu ago o
jare
Ṣugbọn otitọ ko ṣaiye titun
Bo fẹ lowo nile yi ọmọ Ade
Bo nsotitọ inu, wa pẹ t'ọpe
Bo fẹ lọla nilẹ yi bo sotito
Wa pẹ ko to r'ye jẹun
Otitọ inu saiyekotọ dara
ago
Ọga aiyekotọ binu o ju si
ago irin
Bi o ṣe jẹ nka wi fun ọ
Ọga ko si nile, ile di taya
aisinile ologbo ile di ti eku-
te
Baale lọ nile, ile di ti ale o
jare
Aiyekotọ dakẹ o nkahnu
ọkunrin
Ale sọle dile ero o sọyẹwu
Oju aiyekotọ pọn, o dakẹ
o nwoye.
Aiyekotọ fai dubulẹ o dakẹ
aisan
O tai gbọ iku ara ile omi
nbọ loju
O nkẹdun ọga, o ni iya njẹ
oluwa on
Iyawo ọga ṣire ọwọ nwọn
ṣe toju Nwọn o ṣai ṣe tabe o jare
Ale kuku ri ibi ṣu si o da
wọtele
O jẹun tan o tun jẹ igbadun
si
Bale ko yi wọ ile taiyekotọ
ti figbe ta
O ni "Kabọ kabọ Alabi do
Iya Simbi
Mo ri wọn, mo ri nwọn,
nko purọ"
Ṣaraṣa baba Sinbi sare wọle
Ṣe otitọ koro, o lẹni to le
gba a sara
Inu bi ọga aiyekotọ
O ni o tẹ on nigbangba
O ni ẹiye buburu agbeni
saiye lọwọ
O ni ohun ba wun aya
Wo Oju Ewe Kẹrin

---

AH! REMEMBER THAT

# The Social Dandies

*PRESENTS*

## An Eid–Ul–Kabir Dance

AT

**FORESTER CENTENARY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn.

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing,

## Tickets: 4/- Flat

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ Offices, Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute–Mẹtta.

---

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn

# RICHALẸT

Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣe fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Edọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku t' o wa ninu ẹjẹ ara rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ toritoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu

Bere egbogi ajẹbina Payal yi ni ṣọbu wọnyi:—
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Fai)
(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street, Yaba

# Awọn Oniwe rohin Naijiria Bẹ lẹ Gẹẹsi Wo

LỌNDỌNU:- Irohin kan fi ye wa wipe awọn oṣiṣẹ iwe Irohin ọmọ ilẹ Naijiria mẹta nṣe ibẹwo ilẹ gẹẹsi lọwọ bayi. Ninu irin ajo wọn nwọn yio rin jina lati le ri bi iṣẹ idagbasoke ilẹ Gẹẹsi ti nlọ si, bi ile ẹkọ ilẹ na pẹlu ile Igbimọ Aṣofin ilẹ na ti tiri.

Awọn oniwe rohin mẹtẹta na ni Ọgbẹni C. O. Anyiam ti ile iwe Irohin Nigeria Outlook ni Ipinlẹ Ila Orun, Mallam A. Salihu ti ṣe alakoso eto iṣẹ, ti ile ẹrọ Redio ni Oke Ọya ati Ọgbẹni P. Ugbomoh ti ṣe ọkan ninu olotu irohin Daily Times ni Ipinlẹ Ila Orun.

Larin ọsẹ kan ti wọn de si ilẹ Gẹẹsi ni wọn ti ni anfani ati le ba awọn olori ẹgbẹ oṣelu mẹtẹta ti ilẹ na sọrọ.

Nwọn si tun ti ṣe ibẹwo de ile iṣẹ agba Irohin kakiri agbaiye (Reuter's) nwọn si ti ṣe akiyesi ọna ti wọn fi te iwe jade fun kika ni ilu Oyinbo ti o yatọ si ti wa.

Awọn oṣiṣẹ Iwe Irohin yi si ti tun rin kiri lati le ri nwọn ohun miran ti o wa nilẹ Gẹẹsi.

Lati ilu Lọndọnu ni awọn oṣiṣẹ Iwe Irohin mẹtẹta yi ti lọ si ilu Birmunghan nibiti wọn yio ti ṣe ọsẹ kan ti nwọn o si bẹ ibi iṣẹ Cadbury pẹlu ile ẹkọ giga ti o wa nibẹ wo.

Atun gbọ wipe nwọn yio tun de ile iṣẹ awọn ti o ṣe moto Rover.

Ni ilu Glassow awọn onise iwe Irohin yi yio bẹ ile ise telẹlrisọ wo.

Agbọ wipe nilu na ni wọn yio ti ba oludari iṣẹ ile itẹwe eyiti Ọgbẹni Roy Thoumps n nṣe oludari rẹ jiroro ọrọ.

Ki awọn onisẹ iwe irohin yi to pada si Naijiria nwọn yio tun lo ọsẹ kan ni ilu Lọndọnu ti nwọn yio si de ilu Southampton nibẹ ni nwọn yio ti ba alagba Alderman Ronalp Pagh jẹ ase ọsan.

Lẹhin eyi ni nwọn yio tun bẹ ile iṣẹ ẹrọ Redio N.B.C. ati ile iṣẹ gbogbo ti o wa nibẹ wo.

Nipari irin ajo wọn nwọn yio tun ba awọn ọmọ ile Igbimọ Asofin ilẹ Gẹẹsi jẹun ni ile Igbimọ Asofin awọn Mẹkunnu.

## YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan. 21 - Feb. 19) Maṣe joko lasan bẹrẹ ki o mu iṣẹ kan ṣe lati oni lọ, masi ṣe gbe ti obirin dani loni.

PISCES (Feb. 20 - Mar. 20) Iwọ yio ri irohin ayọ kan gbọ loni, nipa awọn ẹbi ati alagba kan to jẹ tirẹ

ARIES (Mar. 21 - April. 20) Tẹramọ iṣẹ rẹ maṣe fi ṣere nitoripe o daju pe ilọsiwaju yio wa fun ọ loni

TAURUS Apl 21 - May 21) Alagba kan yio pari ọrọ ti o ti wa nilẹ fun ọjọ pipẹ yio si tẹ ọ lọrun

GẸMINI (May 22 - Jun. 21) Idunnu ati ayọ yio de si ọ loni lati inu ile rẹ ṣugbọn lọwọ owurọ ni ki o jade lọ sode.

CANCER (June 22 - July 23) Nwọn o ṣe akoko iṣẹ rẹ ku nipa ke-eta, ati wipe alaimọgiri si nkan lati ọdọ enia rẹ kan yio mu ọ binu.

LEO (July 24 - Aug. 23) Maṣe mogbọn-mogbọn loju ara rẹ bi bẹkọ, iwọ yio sọ ọrẹ atata kan nu. Iwe ti o ngbero lati kọ, jẹki o di ni irọlẹ.

VIRGO (Aug. 24 - Sept. 23) Maṣe rin irinajo lọjọ oni Irin ajo loni ko sunwọn.

LIBRA (Sep 24-Oct 23) Iṣẹ rẹ yio dara pupọ loni ilọsiwaju yio si wa ninu iṣẹ rẹ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Eni kan yio ṣeiranlọwọ fun ọ nipa ohun kan ti o fẹ ṣe.

SAGITTARIUS (Nov.23-Dec.22) Ohun kan ti o fẹ ṣe dara ṣugbọn ki o sọra nipa Amọlu, ki o gba imọran ti ẹlominran yẹwo, ọgbọn ki iṣe ti ẹnikan loni

CAPRICORN (Dec.23-Jan.20) Mase ba obinrin ṣe ṣiṣẹ pupọ loni, ohin ti iwọ ko ba si le ṣe ọ lọṣẹ.

IWI ASIKO LATI OJU EWE KẸTA

ni kọ lo nṣe
Lọga ba faiyekoto sinu ago
Lo ba gbee si igbeku
nitori otitọ.
Ṣugbọn tọga lojuo' ọmọ iya mi
On lo gbena sori ile to sun ọ
Eni kọ otitọ a joro irọ
Eni kọ ibawi ajiya omugọ
Ṣugbọn:-
Orin .
Atori ẹnu aiye
Atori ẹnu aiye o
Ibiti nwọn tẹsi
Ni ko tẹ si.

# Igbimọ Atunto Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

GẸGẸBI a ti fi aṣẹ fun mi lati ọdọ awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe, nwọn ti tu ẹgbẹ Imọlẹ Aiye tẹlẹ ka, a si ti tun da omiran silẹ nitorina ti o ba ri pe o fẹ jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ titun yi ki o kowe si mi ki o si ri pe o wa si Ipade ni ọjọ kọkanla oṣu kẹrin (11/4/64) ni dede agogo mẹta ọsan.

Ẹgbẹ yi yatọ si ti atẹhinwa a si tun ti ni ofin titun miran, Eyi si ni awọn ere ti ẹgbẹ titun na yio ma ṣe.

1. Lati maa kọ awọn ọdọ ilẹ yi ni ọna bi a ti nkọ irohin, itan, ọrọ sinu iwe Irohin lati ọdọ awọn Ọjọgbọn oniwe Irohin
2. Ere bi Bọọlu alafẹsẹ gba, Table Tennis, Swimming, Entertainment, Ayo Iṣẹ, Draft Ludo Picnic ati ọpọlọpọ awọn nkan miran ti ẹ o ma a gbọ ni ipade.

Nitorina ti o ba fẹ tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ titun yi, ki o wa si ipade ni ọjọ 11/4/64 ni nọmba 16, Bamgbose St., Lagos, Ao si tun yan awọn alaṣẹ ẹgbẹ titun.

Eyi ni orukọ awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ:—

1. J. Ọla. Okunlọla
2. Latifu Babalọla
3. Sedu Olupo
4. Abudulahi Awẹlẹnjẹ
5. Timothy Akins

Ẹ jọwọ, ẹ tete de ipade o.

BERE OJULOWO EGBOGI:—

# Congreve's Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikofọ eje lara Inu gbigbona nigbakugba Igba-aiya riru ọmu riro wiwo, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi-oju Ilaogun ara jẹ ẹsẹ ara sisọn, gbori abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun tọju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera idimọ ati orisirisi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

# mmoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orisirisi rọbirọki egbogi ti wọn nko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi iwe egbogi yi bi otutu kọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti ba ba nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danju ni bi oba ti ta de sinsi omi ti o bọwosọ ki o si gbe u sare egbogi otutu ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, to Akokoro, egbogi ti o ma njọ apo-ie-itọ tabi se iwosan iyọnu ayọ-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọwa-ọfun didun ati orisirisi omiran pẹlu bere ni ṣọbu awọn:—

Waterloo Mdicine Stores
8 Palm Chucrh Street, Lagos.
Phone: Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# Asọbade Orire Ere Bọọlu

Reading v Q.P.R. ——1
Shrewsbury v Watford ——x
Walsall v Wrexham ——1

FOURTH DIVISION

Bradford v Southport ——x
Chester v Tranmere ——x
Chesterfield v Barrow ——1
Doncaster v Hartlepools ——1
Newport v Lincoln ——x
Oxford v Aldershot ——1
Rochdale v Carlisle ——x
Stockport v Gillingham ——x
Workington v Bradford C ——x

SCOTTISH CUP — SEMI-FINALS

Rangers v Dunfermline ——1
Kilmarnock v Dundee ——1

SCOTTISH LEAGUE — DIVISION I

Aberdeen v Hibernian ——1
Dundee U v Queen of S ——1
E Stirling v Third Lanark ——x
Partick v Falkirk ——1
St Mirren v St Johnstone ——2

SCOTTISH LEAGUE — DIVISION II

Albion v Berwick ——x
Arbroath v Brechin ——1
Dumbarton v Cowdenbeath 1
East Fife v Clyde ——2
Montrose v Forfar ——1
Morton v Alloa ——1
Stenhousemuir v Ayr ——2
Stranraer v Hamilton ——1

FIRST DIVISION

Arsenal v Sheffield U ——1
Birmingham v Chelsea ——1
Bolton v Aston Villa ——1
Burnley v Stoke ——1
Everton v Blackpool ——1
Fulham v Tottenham ——x
Ipswich v Nottingham F ——2
Leicester v Liverpool ——x
Manchester U v Wolves ——1
Sheffield W v Blackburn ——x
W. B. A. v West Ham ——2

SECOND DIVISION

Charlton v Northampton —— 1
Deby v Leeds ——2
Grimsby v Bury——2
Huddersfied v Rotherham ——x
Leyton O v Swind n ——2
Middlesbro v Scunthorpe ——1
Preston v Manchester City ——1
Southampton v Norwich ——1
Swansea v Cardiff ——x

THIRD DIVISION

Brentford v Southend ——1
Bristol C v Colchester ——2
Coventry v Oldham ——1
Crewe v Hull ——2
Crystal Palace v Bourne Mouth ——x
Luton v Bristol R ——2
Mansfield v Peterborough ——1
Notts Co v Barnsely ——x
Port Vale v Millwall ——2

## Selections

NINE HOMES—Arsenal Everton, Manchester U., Preston, Southampton, Coventry. Reading, Walsall, Doncaster, Next best: Dundee U.

FOUR AWAYS—Nottingham F., Colchester, Hull Bristol R. Next best: Millwall

THREE DRAWS—Leicester, Crystal Palace, Rochdale, Next best: Stockport.

TREBLE CHANCE—Fulham, Leicester, Sheffield W., Derby, C. Palace, Shrewsbury Rockdale, Stockport, Next best: Swansea. Workington.

# Abayori Orire Ere Bọọlu Ọsẹ To Kọja

ENGLISH DIVISION I

Aston V 2 Fulham 2
Blackburn R 1 Everton 2
Chelsea 3 Bromwich A 1
Notth F 3 Sheffield w 2
Sheffield U 0 Leicester C 1
Stoke C 9 Ipswich T 1
Tot'ham H 2 Man'ster U 3
West H U 1 Arsenal 1
Wol'ton W 1 Burnley 1

ENGLISH DIVISION II

Bury 3 Swansea T 2
Leeds U 3 Grimsby T 1
Man'ster C 1 South'pton 1
Norwich C 2 Hudfield T 2
Portsmouth 1 Plymouth A 2
Sunderland 4 Preston N 0
Swindon T 2 Mid'brough 0
Northampton 7 v Leyton O
Late Kick-Off

ENGLISH DIVISION III

Bournemouth 2 Coventry C 1
Bristol R 7 Shre'bury T 0
Col'ster U 1 Crystal P 1
Abandoned after 57 minutes ground waterlogged
Hull City 2 Luthon T 0
Millwall 2 Walsall 1
Oldham A 1 Bristol C 2
Watford 4 C Alexandra 1

ENGLISH DIVISION IV

Bradford C 1 Chester 1
Carlisle U 6 Doncaster R 0
Exeter C 3 Oxford U 2
Gillingham v Bartow postponed
Hart'pools 1 Workington 2
Aldershot v Brighton and Hove
Albion and Halilfax Town V Bradford Evening kick-off

SCOTT ISH DIVIION I

Aberdeen 3 Q of South [illegible]
Air'n ans 5 E. Stirling 0
Dundee 2 Hearts 2
Falkirk 0 Motherwell 4
Hibernian 1 St. Mirren 4
Kilmarnock 4 Celtic 0
Rangers 2 D'mline A. 0
St. J'stone 2 Partick T. 1
T. Lanark 2 Dundee U 3

SCOTTICH DIVISION 112

Aloa A. 2 Albion R. 2
Berwick R. 4 East Fife 0
Clyde 2 Cow'beath 1
Forfar A. vs Ayr U. postponed
Hamilton A 3 Sten'muir 0
Morton 2 Arbroath 2
Raith R 2 Stranraer 1
Stirling A 1 Montrose 1

BI O BA NI

Iwe—Titẹ

FUN

Lilo nibi iṣẹ rẹ tabi orișirisi iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

IWE Igbeyawo

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ERỌ—ITẸWE

Modupẹ Printing Press

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ERỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NBGA

IROHIN KO TO AFOJUBA

Danwa wo Ịẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ

Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"

LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ un wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogboẹda patapata" Amin.

"WAS SALAM"

AKIYESI Gbogbo Musulumi Ododo oyẹ ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA

Iye Owo 5/6, £3 fun dosini

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan

Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara!

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro ilu ko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Egbogi "Ikọ" ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibiti oti joko si ti o si ti gbiyẹ. Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹn bere fun egbogi wọnyi:

"Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi "Linituss"

Fun iwosan iko Asma, ikọ fere iko otutu igba-aiya ikọ egbedu, ikọ-orafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna ọfun tabi pelu kelẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan ati oru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri.

O daju nibẹ iwọ yio bere si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE. TENI GBOGBO LAWA

No. 565 THURSDAY MARCH 26, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti nwọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16, BAMGBOṢE STREET,

PHONE 21985, LAGOS.

# MOTO KAN KOSI ẸNU ỌKỌ RELUWE!

OSHODI:- Jinnijini dabo gbogbo enia nigbati nwọn gburo iku abiyamọ kan Iyaafin Bọsẹde Beecroft ẹni ọdun mejidinlogun ni ọjọ Aje tiṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi. Irohin fi ye wa wipe ọkọ reluwe ni o sọ lu mọto ti abiyamọ yi wa ninu rẹ ti mọto na run womuwomu.

Bi ọkọ reluwe na ti sọlu mọto na ni a gbọ wipe were ni ọmọ ti abiyamọ yi tẹ si ẹsẹ rẹ ba fo jade kuro lọwọ rẹ ti o si ba ilẹ kun mọto jade bọ sinu igbo.

Irohin tun fi ye wa wipe mọto ti Abiyamọ yi wọ daku si oju Irin bi o ti fẹ sare kọja ki ọkọ reluwe na to de ti ko le lọ mọ dẹrẹba mọto na sa gbogbo agbara rẹ lati ti mọto na kuro ki ọkọ reluwe na to de ṣugbọn ko ṣeeṣe.

Bi dẹrẹba mọto ati awọn miran ti o wa ninu mọto na ti ri ọkọ reluwe ti o yọ lọọkan lai tan ina ni nwọn ba sa, ti nwọn fi obinrin abiyamọ yi pẹlu ọmọ rẹ si lẹ ti orun si ti gbe wọn lọ.

Lai fa ọran gun ni ọkọ reluwe ba sọlu mọto na ti o si tẹ gbogbo rẹ ati abiyamọ yi latẹ pa.

Irohin tun fi ye wa wipe ẹni ti o ni mọto yi ni Ọgbẹ ni Adegun ti o nṣiṣẹ nile Ina ilẹtiriki ni Eko.

A si tun gbọwipe lati Ijẹbu-Ode ni nwọn ti nbọ wa si ilu eko lẹhin isinmi ọjọ mẹta ti nwọn gba.

Were ti Iṣẹlẹ buruku yi ṣẹlẹ ni nwọn gbe oku abiyamọ na lọ si ile iṣegun ati ti ọmọde ti nwọn lọ gbe jade ninu Igbo.

A gbọ wipe nwọn ṣe itọju ọmọde na ni le Iṣegun Igbobi. Ki Oluwa dá ọmọ rẹ si o.

## Lati Oju Ewe Kini

Ẹnikẹni lo ni anfani lati le ra ohun ti o ba wu oluwarẹ lai si idiwọ fun ẹlomiran.

Ọlọla Azikiwe wa kesi gbogbo awọn Ijọba Ipinlẹ kọọkan lati le ma a ṣe akiyesi awọn ofin mẹwẹẹwa wọnyi.

Ki olukuluku awọn alaṣẹ eto Ijọba kọọkan o le ma a ṣiṣẹ wọn laiṣegbe, laibẹru ati laiṣe oju saju enia.

Ni ipari ọrọ rẹ Ọlọla Azikiwe wa sọ pe, Ẹnyin Amofin ẹ ha dakẹ ẹ nworan ni? Ẹnyin Alakoso Ijọba tabi ẹ ko mọ wipe itakun to so igba lo so agbe on na tun sọ elegede.

O wa pari ọrọ rẹ bayi pe, "Pẹlẹpẹlẹ di ọwọ nyin o ẹnyin ara ilu."


## Never

refuse a trial run before you choose a car. Let the cars speak for themselves and be scrupulously critical when looking at different models. We are convinced (from long experience) that any Mercedes-Benz will pass such an examination with top marks. Please give us the opportunity of substantiating our claim.

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.



Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, Lagos Phone 21985

Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S. Grammar School) P. O. Box Bariga (26/3/64)